# EKO AKETE.

## IWE IROHIN ỌSỌSẸ.

ỌRỌ IFOJUSUN:—
"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN FUN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".

VOL I. NO. 23. SATURDAY, DECEMBER 16, 1922. FOURPENCE.



*Editor & Proprietor:*—
ADEOYE DENIGA,
*Office:* 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.



ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.


## GBOHUN-GBOHUN.

### A ṢORO ṢE BI ÒWÒ.

A gbọ́ pe awọn oyinbo oniṣòwo ti a npe ni C.B.C.A. ti Opopo Nla nibi, ti "ko 'gba si 'le" lati ẹnu ọsẹ bi mẹta sẹhin. A sọ pe nwọn lu igbèse ti o to £75,000 lọdọ Ile-owó ti "Debi" *(Colonial Bank)* ni Ẹhingbẹti: a si sọ pe orukọ awọn oyinbo titun ti o mbọ wa rọpo wọn njẹ G.C.C.A.

### IYAWO DÙN L' ỌṢINGIN.

Ọgbẹni DANIEL ỌLATUNDE WILLIAMS yio gbe Omidan ADELAIDE ADUKE ADEREMILEKUN WILLIAMS ni Iyawo ni Ile-ìsin Tinubu ni *Wednesday* ọsẹ ti a o bọ si, ni agogo mẹwa-ābọ ni ogunjọ oṣù yi.

Ọkọ Iyawo jẹ ọmọ Ọgbẹni GEORGE O'CONNOR WILLIAMS,
aburo DADDY TOWRY COKER ati obinrin rẹ̀, o si jẹ aburo Ọgbẹni
CHRISTOPHER WILLIAMS ti Ile-iṣẹ Ọba Ijẹri Owó *(Audit Office)*
l' Eko: Iyawo si jẹ ọmọ Mrs. COMFORT ADUNI BAILEY, ati Ọgbẹni
SIGISMUND WILLIAMS olōgbè ti o jẹ́ ọmọ Ọgbẹni Ajiṣefinni
R S WILLIAMS ti Ile-iṣẹ Igboro Ilu *(P.W.D.)* olōgbe. Iyawo na
si tun jẹ aburo Ọgbẹni J. MOSALEWA THOMAS, ti Ile-òwò John Holt
ti Eko, Alawọ Ajidewe, A-pọn-roro bi obùrò. Ki BABA m' ọjọ ró.

## T' ỌMỌ YIO KU T' ỌMỌ YIO YÈ, A O ṢI KI IYA RẸ̀ KU EWU NA.

O jẹ didun inu wa lati jihin pe nigbati Ọgbẹni J. EGERTON SHYNGLE, ti o jẹ Alaga ẹgbẹ kekere ti Ilu fi kọwe si Gomina nipasẹ ti mimu Iwe-ẹ̀bẹ Eleko wa siwaju rẹ̀, esi de pe ki o fi ẹda meji ti Iwe-ẹ̀bẹ na ṣọwọ lati ọwọ Balẹ Ilu, a si ti ṣe bẹ̃.

Njẹ awọn "Falara" enia ti nwọn ti nfẹ̀ fõ bi akọ ọka, lati iwọn oṣù mẹrin tabi marun sẹhin pe Gomina ki yio "pẹkẹ lu" Iwe-ẹ̀bẹ na, ko ha "bolẹ" baun? ẹnu wọn ko wọ 'hò bẹ̃?—Ki a ṣi mã v ó !!!

---

## DARA NI 'JO ỌKUNRIN, A FI OHUN GBOGBO KẸ NI.

A ṣọpẹ lọwọ Ọgbẹni A. FRANZ LAWRENCO ti Ibadan fun iyẹsi nla ti o yẹ ni si nigbati o pe wa ati ọrẹ wa kan si Apẹjẹ alẹ ni ile rẹ̀ ni Gbagi ni ọjọ *Tuesday* ọsẹ ti o kọja, nigbati a fi dakan lọ si Ibadan: o si fi wa mọ diẹ ninu awọn Ojulumọ ibẹ pe awa ni *Editor* "Eko Akete" ti on pãpã si ti ngbà lati ẹhin wa; njẹ ni ede awọn Kiriyo ti mbẹ ni Ibadan, a ki ọrẹ wa Ọsọnú yi, "ẹ ku gbogbo ẹ:" a tọrọ abukun Oluwa si ile ati ọna rẹ̀.

---

## MOSE IRANṢẸ MI KÚ.

A kẹdùn iku *Bishop* WALMSLEY, ti ilu Saro, ti o ṣẹlẹ nibẹ lai pẹ yi. Ọrun rere !!!

---

## EYI WUN MI KÒ WUN Ọ, A JẸUN LỌTỌ̃TỌ̀.

Ile-ẹjọ kekere ti a ti ṣi lọ si Ile Iranti Afari Ogun ni Ẹhingbẹti ni ọsẹ kan ti o kọja tun padà bọ wa si Ita Tinubu: a sọ pe Adajọ kekere, Ọgbẹni H. A. YOUNG wipe ibẹ ko rọ on lọrun fun iṣẹ na: a gbọ pe Ijọba "*hire*" apakan Gbàngàn na fun iṣẹ Kótu kekere ni pọ́nwùn mẹjọ, ṣile mẹfa ati kọbọ̀ mẹjọ loṣoṣu.

## A-JI-SỌ DIDÙN ỌKUNRIN, A MỌ LẸSẸ BI IYAWO.

A ṣe orĩre lati jumọ ba *Archedeacon* OGUNBIYI tiwa rin irin ajo ni ọjọ *Monday* ọsẹ ti o kọja, nigbati a fi nlọ si Ibadan ti on pãpã si nlọ si Abẹokuta,: igbadun irin-àjo na ko lẹgbẹ ẹ jare!

---

## AWỌN AHMADIA ṢE OHUN ÀRA

Ni ọjọ kẹwa oṣù *December*, awọn Ijọ *Ahmadia* fi ipilẹ mọṣalaṣi kan lelẹ ni Ebute Mẹta. Ãgo mẹwa-ãbọ ni ohun yi bẹrẹ, awọn gbajumọ ti a o darukọ wọn ni nwọn wa nibẹ.—

Ọgbẹni Abduls-Salami Sawyerr, (olori Ijọ *Ahmadia* ni Ebute Mẹta,) Ọgbẹni Ajọ[illegible] (Imam kekere) Ọgbẹni Y. P. Ṣodẹyinde awọn Ọgbẹni Ipayẹ, S. L. Apẹni, T. Ade[illegible] Marquis, S. O. Maṣa, Abdul-Karim Tinubu, Ṣonibarẹ, A. B. Danmọla, Hamzat Mọgaji, D. Olokodana ati ọgunlọgọ ero lati Eko ati lati Ebute Mẹta. Awọn Onigbagbọ ti nwọn ni ọkan rere si ijọ *Ahmadia* si dapọ mọ wọn lati mu iṣẹ na l' arinrin.

Ọgbẹni Ṣodẹyinde sọ ninu ọrọ rẹ̀ wipe Mọṣalaṣi ki iṣe fun ọtẹ̀, bẹni ki si iṣe fun ile igberaga, bikoṣe fun ipo ibẹru Ọlọrun.

---

## ÀJEJÉ ỌWỌ KAN KO GBE IGBA DORI

A dupẹ gidigidi lọwọ Ile owo ọgbẹni W. A. Dawodu fun iranwọ £1. 1. 0. ati ọgbẹni alagba kan 5/- ti nwọn ṣe fun wa nipa iṣẹ iwe-irohin yi. Abẹ gbogbo enia l'okunrin, l'obinrin ki nwọn maṣe da awa nikan da iṣẹ nlanla yi, ṣugbọn ki wọn gbiyanju lati "ṣe bẹ gẹgẹ." L'ọtun l'osi ni a ngbọ okiki rere ti iwe yi ti nṣe lati igba ti a ti bẹrẹ rẹ, o nlọ si oṣu mẹta nisisiyi, nitorina, a ntọrọ iranwọ ẹnyin ọmọ iya wa.

## MALU NBỌ! MALU NBỌ!!

Awọn aladugbo Ita wọnyi ni Ebute Mẹta, Sango, Strachan, Jebba ati Griffith ṣaroye jamba nlanla ti awọn malu ti awọn enia nda ni ita wọnyi nṣe; a gbọ pe ọpọlọpọ ọmọde ati agbalagba ni awọn malu wọnyi ti ipa ọna yi ṣe lọṣẹ. Ọna ti nwọn si sọpe o tọ fun dida awọn ẹran oniwo-gagara yi ni ona Itẹ Oku lọsi ọna Ọsa, ati lati ibẹ lo si Ile-didu-mbu ẹran.

A kesi Awo-ita *Town Warden* Ebute-Mẹta ki o ma ṣai bojuto ọran yi.

---

## LAGOS TOWN COUNCIL.

### PUBLIC NOTICE.

The public are requested to take out their Licences for 1923 according to the following Time Table.

All Licences will be issued from the Council Offices, Catholic Mission Street.

No Licences will be issued until the 19th March, 1923, except as follows:—

Market dues, Liquor, Auctioneers and Dog Licences, from 2nd January to 6th January inclusive.

Motor Vehicle, Motor Cycle and driving Licences, from 8th January to 27th January inclusive.

Carriage Bath Chair, Rickshaw, Go-cart, Truck Barrow, Hand Cart, Licences, from 29th January to 10th February inclusive.

Bicycle and Tricycle Licences, from 12th February to 5th March inclusive.

Petrolem Licences, from 6th March to 17th March inclusive.

Licences will be issued each day from 9 a.m. till 12 noon and on Saturdays from 9 a.m. to 11 a.m.

A. W. S. RUMENS,
*Secretary, Town Council.*

Lagos Nigeria,
14th December, 1922.

## LAGOS TOWN COUNCIL.

### PUBLIC NOTICE.

Notice is hereby given that on and after the 1st January, 1923 the following revised Motor Vehicle License Fees, will come into operation in accordance with Regulation No. 26/1922 (Schedule III.)

| | | |
|---|---|---|
| 1. | Motor Cycle (with or without Side-Car) | £1 10 0 |
| 2. | Motor Vehicle weight unladen not exceeding 12 Cwt. | £3 0 |
| 3. | Motor Vehicle weight unladen exceeding 12 Cwt but not exceeding 30 cwt. | £6 6 0 |
| 4. | Motor Vehicle weight unladen exceeding 30 cwt. but not exceeding 50 cwt. | £12 12 0 |
| 5. | Motor Vehicle weight unlading exceeding 50 cwt. | £45 0 0 |
| 6. | Trailer, weight unladen not exceeding 10 cwt. | £1 1 0 |
| 7. | Trailer weight unlading exceeding 10 cwt. | £2 2 0 |
| 8. | Dealers License. | £4 4 0 |

When a License is issued after April 1st and before July 1st, or on or after July 1st and before October 1st or on or after October 1st a reduction of one quarter, or one half or three quarters of the above fees may be allowed respectively.

"Weight" means the weight of the Vehicle exclusive of the weight of any water or fuel.

A. W. S. RUMENS,
*Secretary, Town Council.*

Lagos Nigeria,
14th December, 1922.

## EKO AKETE.

EKO, SATURDAY DECEMBER, 16, 1922.

### IJỌ ỌMỌ-IBILẸ GB' ÀRA DÁ, T' ẸLẸGAN LO KU.

Ninu Iwe-ikede kan ti o to ibora-ọmọ-titun ti awọn akọwe Ijọ Ọmọ-ibilẹ (*Bethel, Salem Zion*) fi si ita ni lọlọ yi, li a gbe ri i ka pe awọn Ijọ na mura ati "ṣe bẹbẹ" lati ẹnu *Sunday* ti o kọja fun ariya ọdun Ikọkanle-logun ti nwọn ti da wà nipa iranlọwọ Ọlọrun gẹgẹ bi Ṣọṣi Ọmọ-ibilẹ. Ti a ba boju wo ẹhin, a o ri pe ọpọlọpọ ọjọ li o ti rọ ti ilẹ ti fi mu, nigbati a ba ro gbogbo wahala, ede-aiyede, ẹjọ orişirişi, ikùn-sinu ati işoro miran li ẹniruru ti awọn Ijọ yi ti rekọja ninu rẹ: eyi ko le şe ko má ri bẹ, nitori ibẹrẹ ohunkohun ti o jẹ rere ni lati fi ori gbá ki nwọn si ri fiti-nọti, ki nwọn to "yege;" ti a ba ri irufẹ inira bayi, awọn ope enia lè pe e ni fifi akoko tafalà, şugbọn loju awọn ọlọgbọn, o jẹ ami ifẹsẹmulẹ nkan na lẹhin ọla ti awọn ti o ba nşẽ ko ba şe ojó tabi ki nwọn "ju okete silẹ."

Nisisiyi ti awọn Ijọ yi ngun oke agbà nigbati nwọn ti di ọmọ ọdun mọkanle-logun bayi, aniyan wa ni pe ki nwọn tubọ mura lati tan Ina-ihinrere Kristi kakiri gbogbo agbaiye, lọna ti AWA ENIA DUDU, ki nwọn si mu gbogbo ohun ti a le ka si alẽbu kuro. Ọdun mọkanle-logun ki işe ọmọde-ọdun ninu igbesi aiye enia: nitorina ni a fi nri awọn ẹlomiran ti nwọn nşe ariya, kete ti nwọn ba ti ni ọdun bẹ lori, ti yio mu wọn di ẹniti a nka kun awọn ti o ngun oke-agbà.

Ninu orişirişi imọran ti awọn ara Ijọ yi yio gbà, ni ajọ Igbimọ wọn ni gbogbo ọsẹ meji ti ariya yi yio gba, adura wa ni pe ki a ma şe ri ẹnikẹni ti yio mã wa ogo ara rẹ bikoşe ogo igbeleke Işẹ Ọlọrun lãrin awọn enia wa ti nwọn şi wà ni ipo abọrişa; nitorina ki ọrọ şoki, a ba awọn Ijọ yi yọ: bẹbẹ ni ki a ma ri; aşeyi ş' amọdun. A si ntọrọ ki OLODUMARE Arinu-rode Olumọ-ọkan ma şai tubọ mã tọ wọn, ki O si mã şọ wọn nipasẹ Işẹ iyebiye ti a ti fi ran wọn lati ode-ọrun wa, tobẹ ti gbogbo ilu Oke yio fi gbojikan fun imọlẹ isin Kristi ti a o ti ipasẹ wọn tan si awọn ara wa wọnyi.

Njẹ, gbogbo ẹnyin Olufọkansin, ẹ jare, ẹ ba wa gbe orin yi. Ẹ má jẹ ko tutu!!!

Ọmọ Oluwa nş' ajọdun,
Orere, ẹ yọ şẹşẹ
Jesu Ọgagun l' O de,
Orere, ẹ yọ şẹşẹ,
Orere o, orere o,
Ẹ lọ gb' aradi, Ọrẹ,
Orere, ẹ yọ şẹşẹ. Aşẹ.

### SUPERSTITION OR SCIENCE.

BY ADEOYE DENIGA.

With the first number of this Magazine, attempt is made by the resourceful and enterprising Editor, for the first time, to my knowledge, in exploding the popular, if somewhat parochial idea obtaining in some of our people, that the preparation of our God-given herbs, vegetables, etc. etc, into medicines for therapuetical purposes is "superstition." We seem to be carried away with the notion,—a false one at that,—that all the white man prepares for health-giving is "science" and that ours is just the reverse: we know, as a matter-of-fact, that instances are not wanting in which medical aid according to the system of the white man completely fails in the attendance of a patient in a very precarious state, whilst native medicines judiciously applied have proved a veritable shield to that patient in his or her hour of trial: this is no reflection on the medical profession, however, as the argument cuts both ways, happily there are some of our countrymen who though valuing the incalculable good inherent in European medicament, are not prepared to brand their own system of medication as haphasard. The aim of this journal is to educate public opinion at home and abroad, relative to the proper study of our herbs having therapeutic virtues in a way that will reflect credit on us a race, and to show the world that, whilst we are ready to learn from foreign institutions, we are not unmindful of making a research

in our own, which ultimately will tend to the improvement of those medicines with healing properties by all students of native Pharmacology and Therapeutics.

[ The above was written by us 21 months ago and for a few Monthly "The African Herbal Messenger Health Review" which was intended for service by Mr. Ojo Cole of this town but which unfortunately failed in its efforts to exist.—ED. E A.]

## GAN NI YA FI JI—IROHIN KO TO AFOJUBA.

Ni ọjọ kẹjọ oṣu yi ni ijọ jimọ *Friday* ni awọn ẹgbẹ Ifẹ obinrin ti ijọ Aguda *Catholic Ladies Friendly Society* ṣe ariya ere kan, ni ile ẹhingbẹti *Glover Memorial Hall* eyiti afi iwe ere na sode wipe iya afin aya Gomina *Lady Clifford*, ni yio ṣe alakoso ere yi, ṣugbọn odun ni pupọ, gẹgẹ bi ati mọ wipe ailera ti mu lọ si ile rẹ; dipo rẹ ni ọgbẹni onişegun ati arabirinn rẹ H. Andrew Foy ṣe alakoso ere yi.

Gẹgẹ bi imura awọn elere yi ti pọ to, nigbati ade ibi ere yi, ni agbọ lẹnu ọgbẹni Albert Carrena wipe aṣọ ti ata ṣẹhin oke ibi ti aṣe ere yi lati mu ere na yẹ *Back ground* wọn ti ji lọ, ṣugbọn sibẹsibẹ, ere yi ikan lo jẹ ninu orişirişi eyi ti a ti wo bọ ninu ọsẹ na, (a ko le wipe aka eyiti ọgbẹni T. K. E. Phillips ṣe alakoso rẹ mọ.)

Ere yi bẹrẹ ni nkan ago mẹsan kọja diẹ ogun logọ enia lo wọ inu ile lati wo ran ere yi, ọpọlọpọ enia lo fẹ wo ere awọn aguda bi o ti ri, ṣugbọn nigbati wọn de ọhun ti wọn ri ere na, wọn wa mọ pe "Koko iwaju ori enmọ ni."

Ọpọlọpọ awọn ti wọn wo apakan ere yi, ki asiko ariya iṣẹju mẹdogun toto wọn tẹ ara wọn lọrun, wọn mọ daju pe owo wọn ko ṣe gbe; nigbati wọn bẹrẹ ere keji, awọn ọgbẹni wa meji Lọya Shyngle ati H. M. wọ ile, ero wọn ni pe eni a pe ko wa bẹ ile wo, ogba atapọ" Ki a ma pa ato wọn joko.

Nigbati ere yi npari lọ, ni alakoso onişegun ati obinrin rẹ dide lọ, asiko kanna ni ọgbẹni ọlọla ati aya rẹ Orişapẹ Ọbasa ti Ikija jade pelu.

A le fi ẹnu le ati ma rohin ere yi bo ti dun to, ṣugbọn bi a ko ba sọ gbolohun meji tabi mẹta to jẹ otitọ o ṣa buku; a ni lati dupẹ lọwọ awọn Sẹkitẹri ẹgbẹ yi aya J. E. de Sant Anna ati aya S. W. Tucker fun minu ere wọn dun ati lọwọ gbogbo awọn obinrin to wa ninu ẹgbẹ yi.

A ni lati dupẹ lọwọ awọn ọdọmọbinrin Claudie Carrena ẹniti o ko idakan ninu gbogbo ere yi afi ẹniti "Oma pẹgan Ajanaku loma ni ohun ri nkan fi ri, bẹni ẹniti omu kunmọ dani ko gbọdọ ṣe ọdẹ erin" ati awọn bi Francisca Caltano Helen Severeno, Layinka Cardoso, F. M. Lawson ati awọn yoku ti wọn gba ere na yọ.

Ati awọn ọkunrin ti wọn ṣe iranlọwọ nipa mimu ere yi dara ninu orin kiko ati ere şişe, H. Campos, Z. P. Lopez, P. Peters, Victor Silva S. A. Jones, Tucker ati awọn miran.

Pataki ohun kini ti a ni lati ṣe akiyesi ni ẹniti o duro lẹnu ọna, ti ko jẹki eşinşin fo sinu ile la lai ri iwe lọwọ, ika to ba to si imu la ma ki si, ọgbẹni Damazio ka pa awọn ọmọta ti wọn fẹ wa fi agidi wọle, ati oluranlọwọ rẹ ọgbẹni E. B. Thompson.

Ekeji:—Ọdọmọkunrin wa Ṣowande ọmọ to jẹ wipe Ọlọrun fun ni ẹbun duru titẹ to si ṣe bi alara kuwala lori duru ati awọn ọgbẹni Willoughby Quist ati awọn miran.

Ẹkẹta:—Ere kole dun to bayi, ka ni a ko ri nkan ta soju; a ni lati dupẹ lọwọ ọgbẹni M. Sho Silva ẹniti o ṣe alakoso ọti tita fun wahala rẹ nipa şişi Ọti ati tita rẹ, ṣugbọn a ko le wa sọ otitọ fun ọgbẹni wa yi, nitori ekiomi kẹbẹ, nipa Ọti sise (*Beer*) ọgbologbo ti wọn ko fun ta, nitori ijọ miran, a mọ daju pe ki ṣe ẹjọ rẹ o, ẹniti o ba mu *Beer* yi yo a mọ daju pe, a ko pẹgan lasan, ati ibi ti efi ṣe ibi tita Ọti yi ko dara to, inu ile lẹ ba bere fun gẹgẹ bi awọn omku ati ẹnigbo ti nṣe,

Ẹkẹta:—a dupẹ lọwọ awọn oni kakaki ati goje ti ọgbẹni Hoquart fun lere orin ijọ didun ti wọn si wa lori.

A bẹ awọn ẹgbẹ yi ki wọn tun ere na pe laipẹ yi, nitori irohin rẹ, ko kere ni ilu, ati lori nkan ti wọn nwa owo na fun, ti wọn ba le gbiyanju ati tun ere yi pe, ki wọn si tẹ sinu iwe wipe ijo yio wa pẹlu ere wọn, wọn ni iranlọwọ pupọ, nitori ogun agbo tẹlẹ ki paro "ni ko jẹki a leJyan gbolohun kan nipa abuku ti ijọ ti ko si ni ọjẹ na.

Nitorina a ma fi oju sode lati ri iwe yin wipe "ere ati ijo yio wa."

A dupẹ lowọ ẹyin ẹgbẹ yi fun inawo aṣọ iyebiye yin ki Oluwa ko busi apo yin, ati ile Ọlọrun yin ti ẹ fẹ owo lati tun kọ, ki Oluwa na ko busi apo olukuluku yin. *Amin.*

KỌLAWỌLE ALAỌ.

## Oran Ilu Nigeria No. 5.

Aṣaro ti ọgbẹni Herbert Macaulay oloye C.E. ṣe lori ọrọ ti Dr. John Randle oloye M.B., C.M. ṣo ni ilu oyinbo ti a tẹ si Iwe-irohin ti a npe ni West Africa ti ọjọ keji oṣu September 1922.

### EBẸ AWỌN ENIA.

Nwọn sọ wipe awọn ara ilu Eko pẹlu igberiko rẹ bi Agbadarigi, Ẹpẹ ati Leke fẹ fi iwe ẹbẹ kan ṣọwọ laipẹ (eyiti awọn ti o f' ọwọ si i ti to ẹgbẹrun mẹrindilogun o le mejileladọta enia) si Sir Hugh Clifford Gomina *Nigeria* nipa *Prince* Esugbayi Eleko, ẹniti Gomina ti ni Ijọba ati awọn onisẹ rẹ ko ni bikita fun mọ.

"Awọn ara ọrun yiò ṣe 'ranwọ bi ọmọ

enia ba bere nitoripe Sanma kanna

ṣa lo bo gbogbo wa."

Esugbayi Eleko ọmọ alade, ọmọ Yoruba tarata ni, awọn ti o si bi jẹ awọn Ọba Yoruba faufau.

Ni 1909, ninu iwe kan ti Ijọba Gusu *Nigeria* ṣe, ọrọ wọnyi ni a sọ nipa awọn Ọba ilẹ Yoruba.

"Iwa ọmọluwabi, ati ifẹran ilu ẹni jẹ nkan meji ti o f'ara han daradara lara orilẹ-ede wọn.

Ki a ko gbogbo wọn pọ, iwa ọmọluwabi awọn oloye ilẹ Yoruba jẹ eyiti ẹnikẹni ni ilu oyinbo le fi ṣe awokọ.

Ohun ti o jẹ ọran ẹdun wọn ni pe, nwọn fẹ ma ṣe ilu wọn gẹgẹ bi iṣe ati aṣa ilu wọn, bi a ba ri pe ko jẹ ohun ti o buru.

Awọn Ijoye ni ọgbọn ati ṣe ilu pupọ. Bi a ba si ntọ awọn ti o gbọn s'ọna, ko ni jẹ iyọnu fun awọn oyinbo alabo wọn lati tọ wọn si ọna ilọsiwaju ati ilaju."

Njẹ Dr. Randle tilẹ le ni ero pe ara ilẹ Yoruba kan le sọ ọrọ wọnyi pẹlu ẹdun ọkan ati oye pe :—

"Ki iṣe pe nko fẹran Ceasar tobẹ, ṣugbọn

mo fẹran ilu Rome ju u lọ."

### AṢẸ TI A FI FUN AWỌN ONIṢẸ TI O NTỌJU ILU.

Mo ro pe ko ni ṣai t' ọna, ti mo ba fi tọwọtọwọ mu oju awọn ti olu-ọla Ọba ni ki o ma tọju ilu *Nigeria* lọ si iwe aṣẹ ti Gomina agba ti *India* ti o fifun awọn ajẹlẹ rẹ ni iwọn adọjọ ọdun ọhun, eyiti o fi iwa atata ti o le mu ilọsiwaju ti o pe 'ye wa ninu ẹniti iṣẹlu rẹ ba y' ọdan.

"Iwe aṣẹ rẹ fun ọ l' aṣẹ lori igberiko eyiti idide tabi iṣubu rẹ le kan alafia awọn ti o ku. Ifihan ati imukuro oniruru iwa irẹjẹ eyiti o buru fun awọn talaka gẹgẹ bi o ti le ṣe jamba fun Ijọba. Ifihan iwa otitọ ati ẹtọ eyiti a ni lati ka mọ ẹniti o ba ti jẹ ọmọ ilẹ Gẹsi; titẹ iwa yi mọ ọkan awọn ti o rẹlẹ ju, mimu ọkan awọn otoṣi enia kuro ninu irẹjẹ ati isọretinu lọ si ominira, ni anfani ti o ni 'ye lori eyiti yiò ba orilẹ-ede wa nipa iwa lakaye ati ọgbọn ti o ba lo.

Jẹ ki a ma ri ọ fanlala, ki o si ma ṣakiyesi iwa awọn ti o ntẹle ẹ. Ma ṣe wa ọna aitọ lati lo 'pọ fun ra tẹ, ki o si ki eyi wọ fun awọn ẹlomiran."

### PARI ỌRAN NÃ B'O TI TỌ.

Ki a tilẹ ni ogun na pari
Bi o tilẹ jẹ pe aṣẹgun nbọ pẹlu igberaga
Pẹlu asia fifẹ lẹlẹ ati ẹṣin ti nyan
Ti ilu si ndun kikankikan
Sibẹsibẹ otitọ yi nkigbe s' oke
Pẹlu ọrọ ti a fi imọlẹ kọ
Ko si ọran ti a ti i pari
Titi ao fi pari rẹ b'o ti tọ.

Bi o tilẹ jẹ pe gigirisẹ arẹnijẹ alagbara
Le ma rin alailera mọlẹ ninu ẹkuru
Ti ohun okiki pẹlu ohun kan
Si npe ni ẹni nla ati olotọ
Jẹ ki awọn ti o nyin ṣ' akiyesi
Ki nwọn si fi awokọ yi siwaju
Ko si ọran ti a ti i pari
Titi ao fi pari rẹ b'o ti tọ.

Jẹ ki awọn ti o ti ṣubu ni igboya
Bi o tilẹ dabi ẹnipe ọta ṣẹgun
Bi o ba ṣ' aidara, bi enia rẹ tilẹ pọ
Ogun na koi pari
Nitori, dajudaju bi arọ ti ntẹle
Akoko ti o ṣokunkun biribiri
Ko si ọran ti a ti i pari
Titi ao fi pari rẹ b'o ti tọ.

Ha ! ẹnyin ti a di ẹru le lori
Ha ! ẹnyin obinrin ti ẹ jẹ ọmọde, bẹni
[agbalagba ni nyin
Ha ! ọkan onisẹ ti a nrẹjẹ
Ẹ ma ba ọgun arẹ na lọ
Eyiti ẹ nba alagbara ti o ṣẹgun ja
Ko si ọran ti a ti i pari
Titi ao fi pari rẹ b'o ti tọ.

(Ella Wheeler Wilcox.)

*Koi ti pari.*

## CLIMAX.

World's wonder hair beautifier for men only.

Will straighten the most stubborn, coarse, or kinky hair in five minutes, make hair lustre and silky, without the least bit grease, absolutely harmless.

Sophia's cream brown Pomade known as a national hair remedy which feeds, nourishes and beautifies the hair, will eradicate dandruff, grow your hair long, lustrous, soft and fluffy for women and men; Also assorted kinds of pomade and toilet soap in stock.

Dipo Tunde, & Co.,
P. O. Box 335,
37, Ajiṣomo Street,
Lagos, Nigeria.


## NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

## AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.


•Are you suffering from impotent sexual nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pill sand get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neuiasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that trouble-some Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

Vidal. R. Cole

"Ajenifuja" Store
P. O. Box 201; 109 Broad Street Lagos.

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER.

OYINBO GERMAN ONIṢOWO NI HAMBURG

fẹ ka sọ fun nyin pe ẹ le wa wo orișirișị irepe ọja pẹlu iwe-ọja on ni.

Ile-Owo rẹ No. 7, Ita Labinjọ, leti Ita William l' Eko.

Yi o tete bojuto iwe ti ẹ ba kọ si i, ti ẹ ba si fi sinu apoti iwe rẹ No. 459, ni ile-ipinwe t'Eko, ati iwe-ti ọja ti enia ba fẹ ranṣẹ lọdọ rẹ. O yẹ ki awọn onibara rẹ tete wa ranṣẹ ọja wọn fun akoko oṣu Awẹ ki o ba le tete de: oniruru ọja lo le ranṣẹ fun ẹnikẹni, o si ni ọgọrọ ọja lorișirișị.

Ẹ wa wo o !!!

**The very Books you need!!**

| | |
|---|---|
| General knowledge Test papers | 1/- |
| Key to above | 2/- |
| Ready's precis and precis writing with key | 3/6 |
| Forks Essays and how to write them | 2/9 |
| Dixon's English Idioms ,, ,, | 2/6 |
| Naneanow's "Notes in Hygiene" | 1/6 |

The "ORA" Book Syndicate,
(P.O. Box 278)
*33, Obun Eko Street, Lagos.*

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Oniṣowo ni 7, Campbell, Street L'Eko.

ni wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ ṣin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni.nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.


## MARRIAGE

Adelaide Aduke Aderemilekun Williams
To
Daniel Olatunde Williams
at Wesleyan Trinity Church Tinubu on Wednesday 20th December, 1922.

## Preachers for To-morrow.

AWỌN ONIWASU ỌLA.

ROMAN CATHOLIC

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. ( MORNING )
Masses Isin Arọ.

6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

( EVENING. )

Masses ( Benediction ) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's ( Lafiaji. )

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENING. 5.45—6.30 p.m.

ANGLICAN

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—St. Paul's ( Breadfruit ) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m.—St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

WESLEYAN

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Bro. Benjamin A. Beckley |
| 7 p.m. | Rev. S. A. Pearce |
| 10.30 a.m.—Ereko | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | Bro. C. W. Faulkner-Shaw |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | „ J. C. Cole |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Bro. Daniel O. Mould |
| 7 p.m. | Rev. D. A. Beckley |

AFRICAN (COMMUNION)

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. Supt. G. A. Oke |
| 7 p.m. | „ J. F. Ogunko |
| 9 a.m.—Erelu | Bro. J. H. Lawson |
| 4 p.m. | Rev. J. F. Ognnko |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. Supt. S. A. Coker |
| 6.30 p.m. | „ N. A. Ọnatolu |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Rev. O. Adefolu |
| 4.30 p.m. | Bro. H. A. Williams |
| 9 a.m.—Ararọmi Church | Bro. E. A. Ojo |
| 4 p.m. | „ John Apena |

EBENEZER

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | „ E. C. Alabi |

BROTHERHOOD

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. Akiremi Davies |
| 7 p.m. (Revival Meetings) | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

St. STEPHEN'S (EPETEDO)

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell.

AHMADIA

6 a.m.—Fajir Service Bro. Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe ( Bamgboṣe Street. )

COLONIAL CHURCH. (ODAN)

A nyan Awọn Alufa si Ile Isin yi lọsọsẹ.

---

BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni

" MAGARINE "

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia usure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai ( Custom Street ) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan ; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo si ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

Ọgbẹni ERIC: JOS: W. LEWIS,

Jẹ ẹniti o gba iwe-aṣẹ Ogun pipọ, o si " Ṣabu" Egbogi Oyinbo si 14, Ita Tinubu nile ọgbẹni J. L. Williams Ologbe, ati si 34, Ita Ọbadina l'Eko

Ọgbẹni na ṣetan lati da enia lohun lọna iṣẹ rẹ.

Lati *Monday* de *Saturday*.

7.30 a.m de 12.30 p.m 2 p.m de 8 p.m

Ni ọjọ ọsẹ lati 6.30 a.m de 8.30 a.m

Owo to ngba ko ta enia lara, ẹ lọ bẹwo,

Ogun rẹ jire.

## "O ŞE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aşẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.

### J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7. Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street,*) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAŞINI-ARANŞO ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati şe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ranşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAŞINI na.

Awọn Oyinbo yi nşe orişirişi Ilẹkẹ alarabara. Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipọn, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AŞIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

### Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owọ pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aşẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO. Ogun rẹ jẹ bi idan.

---

## ILE OWO-ỌJA RIRANŞẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Şẹda, Onini, Owu-Şẹda alarabara, Obun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran d'aradara pẹlu ni lita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kōtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIŞOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Ákan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni *374*. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

---

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nşowo Irin Işẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Işẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

---

## ILE EGBOGI IŞẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si oja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromirẹ. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orififọ. Inuririn, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbogi Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o w~o. Irohin ko to afojuba.

Iwọ ko tilẹ gbo orukọ rẹ ndan?

Işẹ Olodumare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,

*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely:—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams*:—Alawọbata, Eko.

---

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo onisowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorisirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru tọ tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'Eko.

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko. Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

---

AWỌN ẸGBE OYINBO ONIṢOWO TI A NPE NI
E. H. STEIN ARA HAMBURG.
NEUERWALL 16 18. GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranṣẹ ọja fun enikẹni to ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekuro ti a ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo (*Europe*) ni owo ti o jo enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ (*Office*) ni Opopo-nla (*Broad Street.*) ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si (*Porto-novo Market Store*) L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nş' oku l' ọrun?
Ki la ti nş' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?

Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.